# AWON OOGUN LATI SE ITOJU ARUN HIV/AIDS.

By Bronner Gonçalves

O daju wipe sise awari awon oogun ti a le lo lati mu emi awon eniyan ti arun HIV n da laamu je pataki igbese ninu ise isegun oyibo. Awon oogon wonyi je koko ninu itoju awon eniyan to ni arun HIV/AIDS. A ni lati mo daju wipe awon oogun wonyi ko le wo aisan yi patapata, sugbon a maa mu emi eniyan gun si.

Orisirisi awon oogun wonyi lo wa fun lilo, ti okookan won ni ise pato lati se lati gbogun ti kokoro ti o n fa arun HIV. O to orisi awon oogun yi merin ti o ti wa fun liolo bayi. A se akoko iru awon oogun yi jade ni nkan bi ogun odun seyin, sugbon anfaani awon oogun wonyi nipa minu emi eniyan gun si fi ara han gidi ni nkan bi odun mewa seyin. Anfaani yi fara han gidi nigba ti awon dokita bere lati maa pa orisi meji tabi meta awon oogun yi po lati se itoju awon to ni arun HIV yi . Adalu oogun yi se ise lopolopo nitori o dena kokoro HIV lati pa ara da: to bee ti awon oogun wonyi ko ni le ka apa re mo. O ti to orisi ogun iru awon oogun wonyi to wa fun lilo loni, awon kan je eyo oogun kan soso, ti awon miran si wa ni apapo.

Awon ilana wa ki a to le bere lilo awon oogun wonyi fun eniyan. Awon ilana wonyi je orisi meta, eyi si n toni sona lori bibere oogun wonyi, tabi ti o ba sese lati sun bibere awon oogun wonyi si waju die si. Ipo ti alaisan naa wa, iye awon kokoro HIV to wa ninu ara alaisan, ati iye awon eya inu eje ti o n gbogun ti arun, je awon ohun meta lati gbe yewo ki a to bere lilo oogun wonyi fun alaisan. Gbogbo eniyan to ni kokoro HIV ninu ara won ko lo nilo oogun ni kanjukanju. A ni lati ranti wipe awon oogun wonyi pelu ni awon aleebu ti won, ati wipe a ko fe ki awon

kokoro wonyi ni aje sara si awon oogun wonyi ninu ara. Ni ida keji, awon miran beru arun AIDS gege bi won ti beru awon oogun wonyi.

Awon miran ro wipe iku ko jina ti a ba ti bere lati ma lo oogun wonyi. Ko si otito ninu eyi. Awon miran ro wipe lilo oogun wonyi le se idena fun won lati se ise oojo won, won ro wipe won ni lati wa ni ile iwosan ni igba gbogbo lati lo oogun yi. Ko si otito ninu awon nkan bayi. Oogun onikoro ni awon oogun wonyi, eyi ko si fa idiwo fun awon ti o ni lati lo won.

Ni awon igba miran , a ni lati yi iru awon oogun wonyi ti a n lo pada. Eyi maa n waye ninu idaji awon eniyan to n lo awon oogun yi ni odun akoko ti a bere oogun wonyi. Awon aleebu ti oogun yi le mu wa bi yiya igbe gbuuru, aito eje ninu ara, arun isan ara ati bebe lo, je awon idi ti a fi le ni lati paaro awon oogun yi. Awon aleebu to tun buru ju awon ti a ti so oro won tele, ati ai le sise oogun yi ninu ara bi akoko ti a bere won , je awon idi ti a fi le ni lati paaro awon oogun wonyi pelu.

Bi o ti le je wipe awon oogun wonyi ti se anfaani to po fun awon eniyan to ni arun HIV, o seni laanu wipe riri owo lati ra awon oogun wonyi je isoro nla ni awon orile ede ti o si n dagba soke ni agabye. Gege bi awon ajo UNAIDS ti fi ye ni ni odun 2006, o fere to ogoji milionu eniyan to ni arun HIV ni agabye , ti opo ninu awon eniyan wonyi si wa ni awon orile ede to si n dagba soke. Die ninu awon eniyan wonyi lo si n ri awon oogun yi lati lo. A ni ilo awon oogun wonyi lati pese itoju to peye fun awon ti arun yi n yo lenu. A ko le mu emi awon to ni arun HIV/AIDS gun si, a fi ti a ba le pese awon oogun yi bi o ti ye.

**Translated into Yoruba Language by:**
**Dr. ADEOTI, Abolaji.**
**Pretoria, South Africa.**
**7th, Nov. 2007.**